# A RÁN AWỌN APỌSTELI MEJILA JADE

## Matteu 10:1-42

### ẸKỌ 81 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Nitori àjaga mi rọrun, ẹrù mi si fuyẹ" (Matteu 11:30).**

**I Ipè Awọn Ọmọ-Ẹyin Mejila si Iṣẹ Iranṣẹ**

1. A fi agbara wọ̀ wọ́n lati ṣe iṣẹ ti a pè wọn si, Matteu 10:1; Marku 3:14, 15; Luku 9:1, 2
2. A ṣe akọsilẹ orukọ awọn mejila naa ti a pè ni Apọsteli, Matteu 10:2-4; Marku 3:16-19
3. Iṣẹ iranṣẹ wọn, si Ile Israẹli nikan ni, Matteu 10:5, 6; Romu 1:16

**II Ẹkọ nipa Iṣẹ Iranṣẹ Wọn**

4. Wọn ni lati waasu ki wọn maa ṣe iwosan lai gba ohunkohun, Matteu 10:7, 8; Marku 16:20; Iṣe Awọn Apọsteli 20:35
5. Wọn kò gbọdọ mu owó lọwọ tabi aṣọ miiran pẹlu wọn, Matteu 10:9, 10; 6:31, 32; Luku 10:3-7
6. Wọn ni lati gbé ni ile ti a ba gbà wọn si, awọn ẹni ti o ba si kọ̀ wọn ni a oo dá lẹjọ, Matteu 10:11-15; Iṣe Awọn Apọsteli 13:51; I Kọrinti 9:14; Luku 10:10-12

**III Inunibini ati Ewu**

7. Gẹgẹ bi a ti ṣe si Oluwa wọn, a o korira wọn lati ọdọ gbogbo eniyan nitori Ihinrere, a o si mu wọn lọ siwaju igbimọ, Matteu 10:16-25; Luku 10:3; Johannu 15:18; 16:33
8. Akoko kan n bọ̀ nigba ti a o fi iwa olukuluku hàn, Matteu 10:26, 27; I Kọrinti 3:13; Romu 2:16; Oniwasu 12:14
9. Wọn ko gbọdọ bẹru eniyan bikoṣe Ọlọrun, Ẹni ti O n kiyesi iṣubu ologoṣẹ, ti O si n ṣe itọju awọn ọmọ Rẹ̀, Matteu 10:28-31; 6:25-33
10. Ere wà fun ijẹwọ Kristi ni igbangba, egun fun sisẹ Ẹ, Matteu 10:32, 33; Ifihan 3:5; Luku 9:26; Titu 1:16
11. Awọn ara ile wọn ni yoo jẹ ọta wọn, Matteu 10:34-37; Romu 8:35
12. Ẹmi aimọ-tara-ẹni nikan jẹ amuyẹ ti kò ṣe e má ni lati le jogun iye ainipẹkun Matteu 10:38, 39; 16:24, 25; Marku 8:34, 35; Matteu 6:19, 20; Luku 12:33; Johannu 12:24-26
13. Ibukun yoo wá sori awọn ti o gba awọn iranṣẹ Rẹ̀, Matteu 10:40-42

## ALAYE

**Oko Pọ́n fun Ikore**

Ṣaaju ki Jesu to rán awọn ọmọ-ẹyin mejila jade, ọwọ Rẹ̀ kún fun iṣẹ pupọ lati maa wo olokunrun sàn, ati lati lé awọn ẹmi eṣu jade. Awọn eniyan pupọ ti yi I ká. Aanu ṣe E, O si wi fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe: "Lõtọ ni ikorè pọ̀, ṣugbọn awọn alagbaṣe ko to nkan; nitorina ẹ gbadura si Oluwa ikorè ki o le rán awọn alagbaṣe sinu ikorè rẹ̀." Aisan ẹmi n ṣe awọn eniyan naa pẹlu; wọn n fẹ "oniṣegun" kan. Ireti wọn ti kú; wọn n fẹ́ isọji.

Ẹgbẹẹgbẹrun ọdun ti kọja a si ri i pe ipo kan naa ni aye wà lonii. Ipe fun awọn alagbaṣe n jade sibẹ; oko ikore pọ́n ṣugbọn awọn alagbaṣe kò to nnkan. A o ha joko lasan ki a maa wò bi awọn eniyan ti n ṣegbe, lai sa ipá wa lati tan Ihinrere kalẹ?

**Pipe Awọn Ọmọ-Ẹyin**

Jesu n rin lọ leti okun Galili ni ọjọ kan, O si ri Peteru ati Anderu wọn n pa ẹja. O pe wọn kuro nidi àwọ̀n wọn lati tẹle Oun. Loju kan naa wọn fi àwọ̀n wọn silẹ wọn si tẹle Jesu. Bi O ti lọ siwaju diẹ si i, O ri Jakọbu ati Johannu n rán àwọ̀n wọn ti o faya, O si pe wọn pẹlu lati tẹle Oun. Loju kan naa wọn fi àwọ̀n wọn silẹ, wọn si tẹle Jesu. Ẹ wo bi wọn ti jẹ ipe Ihinrere! Ẹmi Ọlọrun n kan ilẹkun ọkan olukuluku eniyan lonii. O ṣe ni laanu pe awọn eniyan diẹ ni o n fi gbogbo nnkan silẹ "lojukanna" lati tẹle Jesu!

A ri i pe a pe awọn ọmọ-ẹyin miiran lati ibi oniruuru iṣẹ gbogbo – Matteu lati ibi gbigba owo bode. Gbogbo wọn ni wọ́n ṣe ẹlẹri iṣẹ iranṣẹ Jesu ati bi O ti n wo olokunrun san. Akoko kikọ́ ẹkọ ni eyi jẹ́; ọmọ-ọwọ ninu Kristi ni wọn jẹ, wọn si gbọdọ gba itọni ninu ododo. Paulu wi pe, "Ki enia Ọlọrun ki o le pé, ti a ti mura silẹ patapata fun iṣẹ rere gbogbo" (II Timoteu 3:17). A sọ fun ni pe imurasilẹ fun iṣẹ iranṣẹ ti o dara ju lọ ni pe ki a sunmọ Ọlọrun ki a si ni ibarẹ́ ati ibalo pẹlu Rẹ̀.

**Awọn Ẹkọ Rẹ̀**

Awọn ọmọ-ẹyin wọnyii kò gba ẹkọ wọn lati ile-iwe giga fun ẹkọ nipa iṣẹ alufaa gẹgẹ bi aṣa igba isisiyii, ṣugbọn a kọ́ wọn nipa idapọ ati ibalo wọn ojoojumọ pẹlu Jesu bi O ti n bá iṣẹ Rẹ̀ lọ kaakiri. Nigba kan Jesu dupẹ lọwọ Baba nitori O pa nnkan wọnyii mọ́ kuro loju awọn ọlọgbọn ati amoye O si ti fi wọn hàn fun awọn ọmọ-ọwọ -- awọn onirẹlẹ ti yoo gba otitọ gbọ́.

Ninu awọn ṣọọṣi ti aye ode oni, nini ẹkọ giga ati ọgbọ́n aye ṣe gunmọ loju awọn eniyan, eyi si n jẹ ki wọn ṣe ainaani ohun ti i ṣe ti Ẹmi Ọlọrun ati didi atunbi tootọ́. Jesu wi fun Nikodemu pe, "Bikoṣepe a tún enia bí, on kò le ri ijọba Ọlọrun" (Johannu 3:3). Lonii a le ni idapọ pẹlu Jesu nipa didi atunbi.

**Awọn Apọsteli**

Ọmọ-ẹyin ni a kọkọ pe awọn mejila wọnyii. Nisisiyii a rán wọn jade lọ a si pè wọn ni Apọsteli. Ọmọ-ẹyin ni ẹni ti o gba ẹkọ lọdọ ẹlomiran ti o si n tẹle e; apọsteli ni ẹni ti a rán jade lọ. Ipe ọmọ-ẹyin ni lati kọ́ ẹkọ; ipe apọsteli ni lati jade lọ.

Jesu kò ṣeeṣi yan awọn mejila lati pilẹ Ijọ Rẹ̀. Iye wọn bá ti awọn baba nla mu ti wọn di ẹya Israẹli mejila. Ninu iwe Ifihan a sọ fun wa pé orukọ awọn Apọsteli mejila wà lara okuta ipilẹ Jerusalẹmu Titun.

A to orukọ awọn Apọsteli ni meji-meji o si le jẹ pe a rán wọn lọ gẹgẹ bi a ti tò wọn ni meji-meji.

**Awọn Ju Ṣaaju**

Kristi tọ awọn ti Rẹ̀ wá -- awọn Ju. Awọn ni o doju iṣẹ iranṣẹ Rẹ̀ ni ayé kọ. O kọkọ rán awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ si awọn Ju ṣaaju; ṣugbọn nitori aigbagbọ ati kikọ Kristi, a mu Ihinrere lọ sọdọ awọn Keferi. Paulu sọ pe, "Nitori emi kò tiju ihinrere Kristi: nitori agbara Ọlọrun ni si igbala fun olukuluku ẹni ti o gbagbọ́; fun Ju ṣaju, ati fun Helene pẹlu" (Romu 1:16).

Kristi ko fi otitọ du awọn Keferi nigba ti wọn wá sọdọ Rẹ̀. Nigba ti obinrin ara Kenaani ti ara ọmọ rẹ̀ kò dá tọ Ọ wá, Jesu sọ fun un pe kò tọ lati fi akara awọn ọmọ fun aja. Obinrin naa dahun pe, "Bẹni, Oluwa: awọn ajá a ma jẹ ninu ẹrún ti o ti ori tabili oluwa wọn bọ́ silẹ" (Matteu 15:27). Jesu yẹ́ igbagbọ́ rẹ̀ si O si mú ọmọbinrin rẹ̀ lara dá. Keferi ni obinrin naa i ṣe ṣugbọn o ti mọ otitọ gẹgẹ bi ọrọ ti o sọ wọnyii ti fi hàn.

**Àṣẹ fun Iṣẹ Iranṣẹ Wọn**

Wọn kò gbọdọ mu wura tabi fadaka ninu asuwọn wọn, tabi àpo fun irin-ajo wọn: "nitori onjẹ onişẹ yẹ fun u." Wo bi o ti yatọ si igbekalẹ eto isin ti aye lọjọ oni! Awọn ajihinrere miiran lode oni maa n beere idaniloju iye owo oṣu wọn ki wọn to bẹrẹ iṣẹ.

Ilukilu ti wọn ba de wọn ni lati beere ẹni ti o yẹ lati bá gbé, nigba ti wọn ba si wọ ile kan bi a ba gba wọn ki wọn duro nibẹ, ki wọn jẹ ki alaafia wọn wa lori ile naa; ṣugbọn bi a ba kọ̀ wọn, ki wọn gbọn ekuru ẹsẹ wọn silẹ, fun ẹri si ile tabi ilu naa.

"Wo o, mo rán nyin lọ gẹgẹ bi agutan sãrin ikõkò." Lati igba ti awọn baba nla akọkọ ti ṣẹ̀, ni ogun ti bẹrẹ si jà ninu aye laaarin agbara okunkun ati ti imọlẹ. Jesu gba awọn Apọsteli niyanju pe ki wọn ki "gbọ́n bi ejò" – ki wọn wà ni ojufo lati mu gbogbo anfaani ti wọn ri lò lati jẹri nipa Oluwa wọn. "Ẹniti o ba si yi ọkàn enia pada, ọlọgbọ́n ni" (Owe 11:30) Wọn kò si gbọdọ jẹ́ òpè nipa ti arekereke eṣu. Sibẹ naa wọn gbọdọ jẹ́ "oniwà tutù bi àdaba" -- iwa tutù ati irẹlẹ nigba ifinişẹsin ati inunibini. Jesu kilọ fun awọn Apọsteli pe wọn yoo ṣe inunibini si wọn nitori orukọ Oun, wọn yoo si mu wọn lọ siwaju ajọ igbimọ; ṣugbọn O sọ fun wọn pe wọn kò gbọdọ bẹru nnkan wọnyii. A ko gbọdọ bẹru awọn ti n jẹri èké si wa, nitori Ọlọrun yoo dá awọn olododo lare. Ọjọ kan n bọ̀ nigba ti Ọlọrun yoo tú aṣiiri eniyan, iṣẹ olukuluku eniyan yoo si fara hàn boya ti Ọlọrun ni. Wọn gbọdọ waasu ẹkọ ti wọn ti kọ́ lọdọ Jesu ni gbangba jakejado gbogbo agbaye, lai bẹru awọn ti yoo ṣe inunibini si wọn, nitori Ọlọrun n ṣẹṣọ lori wọn, kò sì sí ẹni ti yoo le fọwọ kan ẹmi wọn. Ọlọrun, Ẹni ti o le pa ara ati ọkàn run ni ọrun apaadi nikan ni wọn gbọdọ bẹru.

Awọn ara ile eniyan ni yoo jẹ́ ọta rẹ̀. Nigba miiran onikupani wa ti o buru ju lọ, yoo jẹ́ lati aarin ẹbi wa. Nigba miiran ile naa a pín si meji: awọn obi a doju ija kọ awọn ọmọ, awọn ọmọ a si doju ija kọ awọn obi, nitori awọn kan ti ri igbala, wọn si gba Jesu gbọ́, awọn miiran si kọ Ọ.

Lẹyin ti o ti fi iṣoro ti o wà ninu gbigba Ihinrere han awọn Apọsteli, Jesu sọ ti ifẹ ati aabo Baba wọn ọrun lori wọn, O tun mu ki o dá wọn loju pe kò si ẹyẹ ologoṣẹ kan ti yoo já lulẹ lai jẹ pe Oun mọ nipa rẹ̀, ati pe wọn ṣe iyebiye ju ologoṣẹ pupọ lọ.

Aṣẹ ti a fi fun awọn mejila wọnyii kun fun imọran rere fun wa lonii: lati "gbọ́n bi ejò ati oniwà tutù bi àdaba"; lati maa reti iṣoro; lati gbẹkẹ le itọju Ọlọrun fun awọn ti Rẹ̀; ati lati tẹju mọ opin irin-ajo wa.

A gbọdọ jẹ oloootọ si ipè ti Ọlọrun pè wá, ki a si dí àyè wa ninu iṣẹ Ihinrere, boya o tobi tabi o kere; ki a maa fi suuru gbé agbelebu wa lojoojumọ -- eyi ni ipọnju ati iyiiriwo – ti o n wá sọdọ wa ninu ṣiṣe iṣẹ́ wa ninu ile, ni ṣiṣiṣẹ lati pese fun aini wa nipa ti ara, tabi ninu iṣẹ Ọlọrun gan an: ati ni jijẹ oloootọ si odiwọn ododo Rẹ̀; ni wiwá alaafia awọn ẹlomiran nigba gbogbo lai si imọti-ara- ẹni nikan.

**Ijọba Ọrun**

Wọn ni lati jade lọ ki wọn si waasu pe "Ijọba ọrun kù si dẹ̀dẹ." Jesu ati Johannu Baptisti pẹlu ti waasu ohun kan naa. Ko si iwe-iroyin, redio tabi oniruuru ẹrọ lati fi tan iroyin kalẹ; ọrọ ẹnu ni wọn gbọdọ maa fi tan ihin ayọ̀ naa kalẹ.

O ti fi owe sọ fun wọn nipa ti ijọba ti Oun yoo gbé kalẹ lọgbagade nigba ti akoko ba to. O sọ nipa ti baale ile ti o lọ si ilu okeere fun ọjọ pipẹ́, lati gba ijọba fun ara rẹ̀ ki o si pada. Kristi wà ni "ilu" naa nisisiyii; O fẹrẹ pada bọ̀ wá gba ijọba Rẹ̀, fun eyi ti O ti sanwo irapada araye pẹlu Ẹjẹ Rẹ̀. Nigba naa ni Oun yoo jokoo lori itẹ ijọba Rẹ̀. Anfaani wo lo to bayii fun wa lonii lati gba Ihinrere ologo yii ati lati mura silẹ lati gba Ọba nla yii nigba ti O ba pada wa fun awọn ti Rẹ̀!

**AWỌN IBEERE**

1. Darukọ awọn Apọsteli mejila.
2. Awọn ta ni a rán Apọsteli mejila naa si?
3. Ki ni de ba ile ti o ba gba wọn?
4. Bi ilu kan ba kọ̀ lati gbà wọn, ki ni awọn Apọsteli gbọdọ ṣe?
5. Njẹ alaafia ni Oluwa mú wá si ayé tabi iyapa?
6. Ipo wo ni o yẹ ki a fi baba ati iya wa si ninu ọkàn wa?
7. Ki ni ṣe ti awọn Apọsteli kò gbọdọ beere owó fun wiwaasu Ihinrere?
8. Nigba ti Jesu rán awọn Apọsteli lọ waasu, awọn meloo ni wọn ni lati lọ papọ̀?